Dajudaju Ọlọhun maa n jowu, ati pe dajudaju olugbagbọ naa maa n jowu, owu jiję Ọlọhun ni ki olugbagbọ maa ṣe nnkan ti Ọlọhun ṣe ni eewọ fun

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikę Ọlọhun ati ọla Rę maa ba a- sọ pé: "Dajudaju Ọlọhun maa n jowu, ati pe dajudaju olugbagbọ naa maa n jowu, owu jiję Ọlọhun ni ki olugbagbọ maa ṣe nnkan ti Ọlọhun ṣe ni eewọ fun".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikę Ọlọhun ati ọla Rę maa ba a- n sọ pe dajudaju Ọlọhun maa n jowu, O si maa n binu O si maa n korira, gęgę bi olugbagbọ naa ṣe maa n jowu, ti o si maa n binu, ti o si maa n korira, ati pe okunfa jijowu Ọlọhun ni ki olugbagbọ ṣe nnkan ti O ṣe ni eewọ ninu iwa ibajẹ gęgę bii ṣìná ati ki ọkùnrin maa ba ọkùnrin lò pọ̀, ati ole jija ati ọti mimu, ati eyi ti o yàtọ̀ si wọn ninu awọn iwa ibajẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3354